# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 911 LAGOS SATURDAY MARCH 7—MARCH 13 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


**Sardauna Ni "Temiyemi"**

# Dokita Okpara Kawo Ija Lori Nipa Oro Enia Kika

ENUGU —Iyọrisi enia kika ti nwọn ka ni Nigeria ni ẹdun ti o kọja ti jẹki ilu da si meji nisisiyi ọrọ na wa di ọkọ nleri iyawo paapa nleri orisirisi ọkan-kojọkan ọrọ ni ọpọlọpọ awọn oṣelu wa si ti nso si ara wọn lori iwe iyọrisi awọn enia kika na ti nwọn gbe jade.

Eti ọlọla Tafawa Balewa si ti kun fun ileri olukuluku wọn nle nipa ọrọ enia kika na. Dokita Okpara ni nwọn ko ba ka irinwo ẹru le iwe iyọrisi enia-kika na lori on ko ni gba fun Ijọba Ipinl Ila Orun ti on ṣe olotu fun rara.

Ọlọla Alhaji Bello, Sardauna Sokoto ni ṣe ẹniti a ri ni a nmọ loju, o ni boya ni on yio wa si ipade ki pade ti nwọn ba pe lori ọ r ọ enia-kika na l'Eko nitripe nwọn ti ka awọn enia perepere, nkan ti awọn akọwe akanja ri ka ni nwọn gbe j de.

A gbọ wipe Ọlọla Alhaji Bello, Sardauna Sokoto ti kọwe si gbogbo awọn Ọba ti o wa ni Oke Ọya wipe ki awọn wa jiroro lori ọ r ọ enia-kika na.

Irohin nla ti a tun gbọ lati Kaduna loru ana ni

(Wo iyoku loju ewe kejọ)

## Ipinya De Ba Awon Ara Ilu Sardauna

KADUNA — A gbọ wipe awọn ara Oke ilu Kamẹru, ilu kan ti a ṣẹṣẹ gba mọra nigba ti awọn ara Kamẹru sọ wipe awọn fẹ wa ni gedegbe fun ara wọn, ti a sọ ni Ilu Sadauna, ti bẹrẹsi fi ilu na sile, olukuluku wọn si nsalọ si ilu Kamẹru ti o gbe wọn.

Onirohin wa ni ọrọ na jẹ kayefi fun awọn ara wa ni Oke Ọya ti o fi de ibi ti nwọn bẹrẹsi sọrọ awọn isansa na ni ile igbimọ awọn Ijọba Ariwa ni Kaduna lana.

Mallam Momodu Nuru Alikali ọmọ ẹgbẹ NPC ti o kọ fẹnu kan ọrọ awọn isansa ti o nfi ilu na silẹ ni ko ye awọn si nkan ti awọn enia na ri ti nwọn fi nsa kuro ni ilu na.

Ọgbẹni Nura Alikali ni nṣe ni nwọn ngba wọn lọwọ lẹsẹ si ilu Kamẹru ti nwọn nsalọ na. Ijọba ilu tuntun na ni ki nwọn ma san owo ori, nwọn si un nfun wọn nile lọfẹ.

## Awon Sanmori Eko Nre Meka 'Alalobo'

EKO— Irohin nla kan ti a gbọ leru ana ni ti awọn sanmọri ọdọmọkunrin pelu awọn obinrin Eko ti nwọn fẹ lọ si Mẹka lọdun ni, ninu awọn ti akọwe onirohin wa gbọ wipe awọn ti palẹmọ awọn amura lati lọ ni Ọgbẹni (lọya) I.A.S Adewale.

Onirohin wa ni awọn ti on tun le da orukọ ni A.R Amusa ọga kan n bi iṣẹ L E D B, M K Fashọla Ọgbẹni A K Agoro (ọdọmọde Kontrakitọ) M O Dabiri, Ọgbẹni Agiri t ijọ awọn Amadiya, pelu Baba ile Ijaiye ni Oke Arin, Ọgbẹni Fas na.

Nina agbo ile awọn ara Ijaiye ni a tun gbọ wipe iya ẹlẹran, iya Wu lia Ọffin, Awanutu Badiru ti mura tan lati lọ si Mẹka ati Medina.

## Mama King Jalaisi Ni Olowogbowo

EKO...Awọn Yoruba ni ma fi ọrun yọ mi, gbogbo wa ni a jọ nlọ ṣugbọn bi ki arugbo wa ku ki a ma sọkun kọ. iyẹn ni ti iya wa, Ellen Sulọla King ti o jalaisi ni ijẹta niau ile rẹ ni 8, Oke Olowogbowo l'Eko.

Ẹni ọdun mejilelogorin ni iya na, o si jẹ akọbi ọm binrin Ologbe Akodu Elliott. Ṣ... ko ... e ni baba k... a ma ni iya-awọn ẹbi Ogunbiyi ni Isalẹ Eko ni iya ti o bi ologbe na ki Ọgbẹni Emmanuel King to g e ni arede ni Ṣọṣi Olowogbowo.

Fun gbogbo igba ti MAMA AGBA (gẹgẹbi awọn ara adugbo ti nma pe e) ṣe laiye ni iwaju ijọ ni'o jẹ ni Ṣọṣi awọn Methodist ni Oke Olowogbowo.

Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ki awọn ẹbi Elliot, awọn bi mama Tayọ (Mrs Macaulay) awọn Ọgbẹn Henry, Akinfẹnwa, Yanju, Akintunde, Pẹkun Elliot' Ọgbẹni T. Olu Johnston, A. B. A J. hnston, ọga pataki ni ile iṣẹ Ijọba ni Ibadan.

Awọn arabinrin Dupẹ Savage, Tayọ Macaulay, Ọmọlolu Ogundipẹ, Yebọ Awoṣika ati Kofoworola King pe nwọn ku idele. Iya na a ranti gbogbo wọn si daradara o.

# Nigeria's Aluminium Gas-Pipe First In Africa

LONDON — The development of industry in Eastern Nigeria at the town of Aba will be aided by the supply of natural gas from the Shell-BP Port Harcourt oilfields.

'It will be the first time that the company has supplied natural gas to Nigerian industry and the first time in Africa that a major gas pipeline will be constructed from aluminium' a Shell-BP spokesman said. Work on the eighteen mile line will start this month and be completed in the middle of July.

The pipeline will be relatively free from corrosion under the conditions existing along the proposed route and will thus not require an asphalt coating.

Th last three miles of the pipeline, which starts at waza near the Imo river, be made of steel to facilitate further connections.

## Action On Cyprus Welcomed In London

London — The Security Council's adoption of the resolution on Cyprus was welcomed in London last night by the British Prime Minister, Sir Alec Douglas-Home.

In a statement from NO. 10 Downing Street the Prime Minister said: 'Her Majesty's Government have learnt with great satisfaction of the proceedings at the Security Council of the United Nations at which decisions were taken to establish an international force to keep the peace in Cyprus, to appoint a mediator, to promote a peaceful solution and an agreed settlement. They will do all in in their power to ensure the continued success of these efforts bring peace to the island'.

The resolution as a whole was dopted unanimously by the Eleven-Nation Council, but earlier, in a separate vote on the paragraph authorising Secretary-General U Thant to appoint the force commander, who would be answerable to him Russia, Czechoslovakia and France abstained.

# Awon Itsekiri Ko Ko Olu Oba Won

WARRI— Lati ọjọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti bọ sori aga Ijọba tuntun ni Ipinlẹ agbede meji Iwọ oran Nigeria ni wahala ti de fun Ọba awọn Itsekiri ti nwọ pe ni OLU WARRI, Ọba Erejuwa Keji.

A gbọ 'rohin wipe ni ọjọ kẹta ti nwọn ti yan awọn alamojuto ijọba na ni ilu Benin ni awọn kan ti wa jiṣẹ fun Ọba na wipe awọn alamojuto Ijọba n o wa foju kan awọn ni Benin ni kiakia, o si lọ sibẹ.

Onirohin wa ni nigbati Ọba na de ilu Benin, awon alagbawi Ijọba kan ni nkan ti nwọn pe si, ni wipe nwọn fẹ ki o lọ f'ori ilẹ rẹ silẹ ni kiakia ti ko ba fẹ ki nwọn wa on kuro nilu na lọgan.



Oloye ARTHUR PREST; ewo ni ẹ mba Ọba Warri ṣe ọrọ rẹ yi.

Gbara t! Ọba Warri na ti gbọ eyi ko fi ọkan pe meji, Ibadan ni o dori kọ, o ṣe to ọsẹ kan nibẹ ki o to pada si Warri.

Nigbati awọn ọta rẹ tun fi oju kan nwọn ni a fi ti o ba fi ilu awọn Obinrin Istsẹkiri ninu pupọju, gbogbo wọn wa fi ọjọ kan kọ ọja silẹ, nwọn ka ọwọ lori nwọn nkọ orin kiri wipe AWỌN NFẸ ỌBA AWỌN AWỌN KO KỌ OLU EREJUWA LỌBA RARA.

Ọmọ Warri kan jii sọ fun wa wipe o ti faramọ awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ (AG) pupọ nigbati nwọn wa lori aga Ijọba lọ eyi si jẹ ki o ni ọta pupọ larin awọn oṣelu ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC).

Inun bini na pọ tobẹgẹ ti awọn ọta Ọba na fi lọ ja ina ati ẹrọ tẹlifonu ti o wa nile rẹ, nwọn ko si tun fun un ni owo oṣu. A gbọ wipe ọrọ Ọba na ṣẹ ndẹrọ diẹdiẹ.

**Plushes, Velvet Velveteen, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, ( Faji Market )

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

**E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI-OFE ti o kun fun irohin aladun losose.**

# Egbe Omo Olofin...

## Ọro Isiri ninu Ipade Idasile Egbe Omo Olofin, ti a se ninu Gbongan Mapo, Ibadan, ni ojo Kokandinlogbon osu February 1964.

A ki gbogbo ẹnyin Ọba, Ijoye, Gbajumọ, l'ọkunrin l'obinrin atį gbogbo ẹnyin ọmọ Yoruba patapata. A dupẹ l wọ nyin fun wahala ti ẹ ṣe ti ẹsẹ fi pe fun ipade pataki yi.

**O wu** ni lorį pupọ tį ẹsẹ pe bayi, t'Ọba t'Ijoye, ti **gbogbo** "Kuootu, Ẹ o jire" pade pọ bayi. O fihan nį **wipe gbogbo** wa mọ riri iṣọkan ilẹ wa. A fẹ ki **o da gbogbo** ijoko loju wįpe gbogbo awọn Ọba ilẹ **Yoruba** ko ni anįy n mįran loni ju bi gbogbo awọn **ọmọ wọn yio ṣe** di ọkan lọ.

A ki gbogbo awọn to ṣe akįtiyan, ti nwọn ṣe lala latį jẹki ẹsẹ ko bayį Olodumare ko ni jẹkį okun i'ẹ to so gbogbo wa pọ ja o, Amin.

A fẹ tẹnumọ ọ wįpe **ipade yi kį iṣe ti ẹgbẹ oṣelu. Ọrọ tį oṣelu tabi ti ẹgbẹ oṣelu** kọ ni a si wa sọ nibį

**Ipade** ti alajọbi ni. I a**de** ti **baba** ati ọmọ ti ọmọ **ni, ipade** ẹgbọn ati aburo **ni. Ẹmi** ọmọlẹbi ni **a** o **si** fi **ṣe gbogbo** iṣẹ to **wa** niwaju wa.

Nitorį omi kanna ni gbogbo įwa mu dagba, orįsun kanna nį a sį ti wa. Ohunkohun to le dabį ẹnipe o fẹ ya wa sọtọ loni, kibaṣe nipa ẹgbẹ oṣelu ni, kibaṣe nipa ẹsin ni, kibaṣe nipa iṣẹ nį, kibaṣe pe nipa ipo nį, ko lagbara to okun alajọbį to so wa pọ lati irandiran.

Ede kanna ni gbogbo **wa** nsọ, gbongbo ka na nį gbogbo wa ni: Ẹ jẹki a gbagbe awọn nkan ti o fẹ ya wa sọtọ, ki a si fi okun ati agbara kun awọn ohun tį o so wa pọ.

Awọn ori wa jakejado ilẹ Yoruba so wa pọ, bẹ nį rara wa, bẹ ni batakoto wa, bẹ ni koso wa bakanna ni dundun wa, aro ati ṣẹkẹrẹ wa. Bẹ ni gbẹdu ati bata wa. A ko tilẹ le **sọ** ti aṣọ ti a nwọ l'ọkunrin atį l'obinrin. Awọn orin wa dabi okun ti o **so** wa pọ jakejado įlẹ Yoruba:

Awọn orişirişi ohun iṣẹ **baiye** ati ohun Iṣẹdalẹ ti **a** nri kakiri ilẹ Yoruba **fihan** pe ọkan na ni gbo**gbo wa**:

Awọn orişirişi tį awọn **baba wa mbọ ki ilaju ti ede oni to de** ati ọna ti **nwọn fi mbọ wọn fihan** pe iya ti o bi aşọ l o bi ẹwu, lo si bi ṣokoto. Işẹ ọwọ atį işẹ ọna wa ko yatọ si ara wọn:

Bawo ni a ṣe le tun wọn ogun nlanla ti a jẹ lati ọdọ awọn baba wa yi şe? Bawo ni a ti şe le pa wọn mọ ti nwọn ma ba parun? Bawo ni a şe le fi wọn le ọmọ lọwọ bi awọn baba wa ti fi wọn le wa lọwọ? Eyį ni įşẹ patakį ti agb jọpọ Yoruba le şe.

O jẹ ohun ibanujẹ fun gbogbo ẹniti o le ronu wipe ede-ai-yede bẹ sile larin awọn ọmọ wa ni nkan bi ọdun meji tabi mẹta sẹhin. Ede-ai-yede y fa ọpọlọpọ rukerudo ti o di işẹ işokan Yoruba lọwọ. Ifasẹhin ti aidọgba yi mu wa s arin ię Yoruba le sọ wa di ero ẹhin. Ọlọrun ko ni sọ wa di ẹni ẹhin o: Amin.



Dokita Majẹkodunmi fi ẹdẹgbẹta ponun (£500) ta Ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin lọrẹ ninu ipade nla ti nwọn şe ni Ibadan:

(wo Iyoku loju ewe kẹfa)

### Iwe Akoka Yoruba

# Ayo Ominira Nigeria

## Lati Owo Aluta ·Atilade

Ki o to to akoko ti Lugard, John Becroft, ẹnitį įşe Aşoju Ijọba Gẹsi, nį Eti Okun Beni ni lati dasi ọran Ijọba Ibįlẹ nį įlu Eko nį ọdun 1851, nįgbati Ọba Kosọkọ le Ọba Akįtoye kuro lori oye, ti ilu Eko. Pẹlu iranlọwọ ọkọ Ogun ti Gesi, John Becroft le Kosọkọ kuro lori oye, o si mu ọ a Akįtoye pada bọ sorį oye. Nitori iranlọwọ yi John Becroft ba ọba Akįtoyi şe adehun ni January 1, 1852 ninu eyiti Ọba na gba pe on yio fi opin si owo ẹru, on yio si dabobo awọn ojįşẹ Ọlọrun ti Isin Igbagbọ lati le ma şe wọn ati pe a o si fi aye gba awọn onişowo Gẹsi lati ma şowo nį ilu Eko. Ni ọjọ 6 August ni ọdun 1861 nį Ọba Dosunmu tọwọ bọ Iwe adehun tį o fi ilu Eko le Ijọba Gẹsi lọwọ.

Gẹgẹbi Ilu Eko ti jẹ ilu owo atį įlu ẹko awọn enįa to wa ngbe įlu Eko latį inu orįşirįşi ilu tį Ilẹ Nįgeria, Liberįa at Brazįl ti lọ siwaju lọpọlọpọ tobẹgẹ tį o fi jẹ pe nigbatį Lugard di Ajẹlẹ Agba ti Apapọ Ilẹ Nigeria ni ọdun 1914, awọn enia ti o ba ni Eko jẹ lọkọ jankan jankan bi awọn olukọ ati oniwe irohin, awọn Lawyer ati Doctor ti nwọn mbere fun ẹtọ l'hun ninu işofin ati idarijį ti Ijọba Ilẹ wa,

Ni ọdun 1820, awọn onşelu ọmọ ibilẹ ti Iwọ Orun Africa se ipade kan (West African Congress, ninu eyiti nwọn ti şe ipinnu pe o yẹ ki Ijọba Gẹsi fi aye fun awọn ọmọ ibilẹ lati le ma ni ohun ninu Ijọba ilu wọn. Ipinnu ti ipade yi ma ki Ijọba Gẹsi yi eto rẹ pada ni Gold Coast (Ghana) ati Nigeria. Ni ọdun 1922, Ijọba Gesi bẹrẹ si ma yan awọn enia lati ma şe aşoju fun awọn ọmọ ibilẹ ninu Igbimọ aşofin ti Ijọba Nigeria. Sibẹsibẹ awọn ẹgbẹ onşelu bi Dẹmọ ti Herbert Macaulay, Nigerian Youth Movement ti Ernest Ikoli, H.O. Davies ati Ọba Samuel Akinsanya ati Ẹgbẹ N.C.N.C ti Oniwe, Nnamdi Azikiwe bẹrẹ si şe akitiyan lati fi ye Ijọba Gẹsi ni Nigeria pe eto ti awọn diẹ ti a daruko lati ọdọ Ijọba yi ko dara to lati şe aşoju awọn ọmọ ibilẹ ninu Igbimọ Alakoso ti Ijọba ti Nigeria Eyi mu ki Ijọba tun şe eto ofin titun ti a npe ni Richard Constitution ni ọdun 1945.

DAGENITE

BATTERIES

give you a longer run for your money!




★ longer life
★ improved electrical efficiency
★ increased shock-resistance
★ fitted with Porvic Separators
★ dry charged

# ELETI-OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kos.'o Sreet, Lagos, B. O. Box 467

CABLE & TELEGRAME "ELETI-OFẸ" LAGOS Phone 23370

VOL. XIV. NO 911 SATURDAY Feb, 15 — Feb 21 1964.


## ORO OLOTU:

# Yoruba Ronu...

Awọn agbalagba ni ilẹ Yoruba n¡ aiye atijọ ni nwon ma nsọ wipe a ki gbọ ¡jangbọn ni emeji n! ile agbalagba. Ọrọ owe yi n¡ ọrọ ti a le sọ fun awọn ọmọ Yoruba ti nwọn pe Aro ati Ọdọfin inu wọn ni ijejo w¡pe o yẹ k¡ awọ ronu, ki awọn jọ pa nkan pọ nitor¡p: ko ye awọn si bi gbogbo nkan na ¡ nlọ si fun awọn larin awọn oṣelu ilẹ Nigerja, ti nwọn si da Ẹgbẹ Ọlọfin sile.

### Eniti Ko Gbon . . .

O to ¡wọn nkan bi ọdun marun tab¡ mẹfa nis¡siy¡ t¡ awọn ẹgbẹ kan n¡nu awọn oṣelu ilu wa ti nsọ wipe awọn ira kan ko nṣe ran rere, ki a ma ba wọn pa nkan pọ rara mọ.

Gbogbo bi awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu na ti nṣe ikilọ bayi fun awọn Yoruba ti nwọn lero w¡pe ko nron, ni awọn ara wa ni nlọ dọbalẹ bẹ wọn n¡ kọkọ, ti nwọn si mba wọn ṣe ilu po.

### Ni Awe Ngbo

Ọrọ na wa fẹ dab¡ ẹniti ko gbọn ti awẹ ngbo tabi ti o n¡ egungun ni ẹr n, ti ko s¡ ju u silẹ. Tani Oluwarẹ ntan? Ara rẹ ni.

N¡ ilu N¡geria b¡ a ba wa awọn enia ti o fẹ a afia t nwọn ko fẹ ij ngbọn, ki a lọ mu awọn Yoruba. Boya eleyi ni o jẹk¡ ọpọlọpọ awọn en¡a ma pe wọn n¡ omugọ.

Tani a ti ba wi bikoṣe awa Yoruba alara paapa ti a ko ni ifẹ ara wa, t¡ o jẹ wipe b¡ o ba ba a, ki o pa a, bi o ko si le ba a, ki o bu u lẹsẹ ni a mba kiri.

Yoruba t¡ d¡ elẹnu meji, boya n¡nu asiko ti a bọ si yi a le pe ọdọfin ati Aro inu wa ki a ronu si gbogbo ire ti o nfẹ fo wa da y¡. Alagẹmọ ni on ti bi ọmọ on tan, bi ko ba mọ ijo jo iyoku kn si ọwọ rẹ.

Ọrọ re o, ẹ y¡n ara wa, YORUBA, Ẹ RONU.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

# Iwe Si Olotu

# Eina Pupo Wa Nilu Hausa

Inu m¡ ylo dun ti ẹ ba le gba mi laye lati le fesi iwe Ọgbẹni Oye Talab¡ ti o jade n¡nu iwe irohin yin ti ọsẹ t¡ o kọja yi.

Ibere Ọgbẹni na ni pe "ṣe awọn Hausa ki ku? ki a mu ti ẹgan kuro, ilẹ oke Ọya jẹ ilẹ ti o to apapọ ilẹ Yoruba pẹlu ilẹ Ibo ni mẹta.

Gẹgẹb awọn oy¡nbo ṣe pin in l ye ati jọ, ipinlẹ mẹrinlẹ ni nwọn pin in s¡.

Ẹ jẹki a ṣe ak¡yesi ilẹ Ilọrin ile Ọffa Igbomina ati awọn Kabba awọn enia ti o wa nibẹ kiṣe kekerẹ rara besi ni ibiti nwọn npe ni Middle Belt nibiti o jẹ kiki awọn onhoho lowa nibẹ. awọn benia ti o wa ni ẹ ju awọn Yoruba lọ.

Bẹna ni ilẹ Borọnu ti o jẹ pe irin ọjọ mẹta ni enia le fi rin ninu mọto. Awọn enia ti o wa ni Kano pọ rẹbẹtẹ, awọn ọba keeke wa nilẹ wọn.

B¡ a ba tun lọ si ile Katsina bẹ ni ao ba a bẹni ilẹ Zaria ti ako le fi ẹnu sọ iye enia ti o wa nibẹ.

Ilẹ Niger ti o jẹ pe kiki awọn Tapa ati Igbira ni nwọn wa nibẹ pẹlu wa lọtọ pẹlu Sokọto ti o jẹ pe Olu ilu awọn Fulani ni titi ti o fi de ipinlẹ awọn Faranse.

Mo fẹ ki ẹ ṣe iranti pe awọn kan ti nwọn tun pọ lọpọlọpọ ni wọn ṣẹṣẹ tun dapọ mọ ilẹ Ariwa ni odun 1962 ni Nortern Cameroon ti o ti wa lara ilẹ Jamani ri. Awọn Aṣoju mẹjọ ni awọn ara ilu na nyan wa silẹ Igbimọ Aṣofin Apapọṣe.

Irọ gidigidi ni lati wi pe ko si enia pupọ ni ilu Hausa.

Mo dupẹ lọdọ Olotu fun aye ti ẹ gba fun mi. Iwaju ni ẹ o ma lọ.

Emi ni,

Eko Duro Ogundele


CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS:
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Steet Lagos.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Oro Enia—kika Fe B'Ige B'Adubi

# Sardauna Ni On Ti Wa Bi Ewa

KADUNA — Ni ile Igbimọ awọn asofin ni Kaduna ni ijerin ọrọ enia kika ti nwọn gbe iyọri rẹ jade laiṣẹ yi, ti Dokita Michael Okpara, olotu Ijọba Ipinlẹ Ila orun ti o tun nṣe olori awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni on ko gba fẹ bi Ige bi Adubi.

Ọlọla Ahmadu Bello Olotu Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni ko si iku ti nwọn fi adiẹ pa ti ko ro ọ lọrun ni ti awọn, o ni nkan ki ti awọn ti nwọn ba sọ wipe awọn ko gba iyọrisi enia-kika na ba ni awọn a ṣe, awọn ti wa bi ẹwa fun wọn, o i bi o ba ti gba ni awọn yio ṣe e.

Ọlọla Ahmadu Bello tun ṣe alaye fun gbogbo awọn ti o wa ninu ile Igbimọ na wipe gẹgẹbi on ti kọ so ninu ọrọ on wipe awọn gba abajade enia-kika na ko si nkan to Ijọba on le ṣe lori rẹ ju wipe ki awọn ma ṣe eto lori nkan aje ti awọn yio ma mu lo fun iye enia ti nwọn ri ka ni ipinlẹ awọn na l .

Ọlọla Bello ni o ya on lẹnu lati ri i ka ninu iwe irohin wipe awọn oṣelu kan ti nleri wipe awọn ko ni abayọri enia-kika na o ni nwọn ko fi ọrọ na mọ ni enia nwọn ka lọdọ wọn o ni gbogbo enia ti nwọn rika ni Oke Ọya ni nwọn bẹrẹsi yọ ṣutu ete si.

Oni oni kọ ni awọn oṣelu na ti ma mbu awọn ti nwọn ma nfi awọn ṣe ẹlẹya ti nwọn ma nṣi ọrọ awọn gbọ, sugbọn awọn nfoju ọrọ wọn da ni nitoripe awọn ko fẹ ija rara.

Ọlọla Bello ni lati igba ti awọn Oyinbo ti nṣe alamojuto Ijọba ilẹ Nigeria ni gbogbo enia ti mọ wipe gbogbo awọn enia ti o wa ni Ipinle Ariwa ju awọn ti o wa ni apa isalẹ Nigeria lọ.



Ọgbẹni JAJA WACHUKWU (Ọkan ninu awọn Olori Ẹgbẹ Alakukọ NCNC)

# Akintola ni On Foro na Han Awon NCNC

Ibadan— Oloye S. L. Akintọla olutu Ipinle Iwọ orun fesi sọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti nwọn jọ nṣe ijọba pọ ni Ibadan, ti nwọn ni ko ba awọn sọrọ iyọrisi enia-kika ki o to so wipe on faramọ bi nwọn ti ka awọn ina na s. Oloye Akintọla ni gbogbo wọn ni awọn jọ pejọ ro ọra na patapata.

O ni bi nwọn ba wa de ipade wọn ni Enugu ti nwọn ṣo wipe awọn ko si nibẹ, irọ ni nwọn npa. Oloye Akintọla ni a jẹ wipe ẹru awọn ọga wọn ni o mba wọn, o ni on ko si le ba wọn wi si eyi rara.

Gbara ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti pada de lati ipade ti nwọn lọ ba Dokita Okpara ṣe ni Enugu ni nwọn ti gbe iwe jade ni Ibadan wipe awọn ko faramọ gbogbo iyọrisi awọn enia ti nwọn ri ka na ki Olotu Ijọba Apapọ se Ọlọla Tafawa Balewa yara pe apejọ awọn olotu ki nwọn tete mọ bi nwọn yio se tete pa ina ọrọ na ki o to da nkan silẹ.

# Eleti-Ofe D'araba





Messrs. Importers, Please Write for Import Information to:

JAPAN BICYCLE TRADE CENTER

P. O. BOX 4117 BEIRUT - LEBANON

# Egbe Omo Olofin

(o bẹrẹ loju ewo kẹta)

Ninu ede-aiyede yi ni awọn Ọba, bi baba nyin ti ṣe akiyesi wipe ẹgbẹ awọn ọmọ Yoruba ti kį i ṣe ẹgbẹ oṣelu ti di meji; eyiti o ti wa tẹlẹ ri, Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa, ati titun tį wọn ṣẹṣẹ da sįlẹ Ẹgbẹ ọmọ Yoruba. Njẹ o ha dara ki a dana ejo kanna lọna meji bi? Iru ẹgbẹ bẹ ti awọn ẹya mįran n Naijįria ko pe mejį. Bi a ba fi nkan na silẹ bẹ, ede aiye de yįo tubọ ma tau kalẹ si nį ị ẹ Yoruba nį Ọlọrun ko ni jẹk a r iru r mọ.

Ki riu rẹ ma ba ṣelẹ mọ lẹhin ti awọn Ọba-Ọba ilẹ fi ori kori ti nwọn si ba ara wọn jiroro nwọn wa ranṣẹ si tun ati ọsi nwọn si pe diẹ ninu awọn enia pataki- ataki ti nwọn jẹ ọmọ Yoruba ti nwọn ko si ni u ẹgbẹ kini tabi ekeji lati wa jumọ jįroro lori ọrọ na. Ki a ;m a ṣ e 'da enna pa ẹnu' tabi ki a maṣe fa ọrọ gun gbogbo nwọn gba wipe o yẹ ki gbogbo ẹgbẹ mejeji ti nṣe ti ọmọ Yoruba di ọkanṣoṣo. Awọn ati Ọba si fi i siwaju awọn ẹgbẹ mejeji wipe bi nwọn di ọkan ki n ọn ma jẹ ẸGBẸ ỌMỌ ỌLỌFIN Agba ko ṣ le wa lọja ki ori ọmọ titun k'owọ.

Ẹni ti njẹ Ọ ọfin na ni baba ati įsẹdalẹ awọn tį nwọn wa nįnu Ẹgb Ọmọ Yoruba. Ẹnįtį nje Ọlọfin kanna nį njẹ Oduduwa tį nwọn n e nį Adįmula. Ẹ ko ha rį bayį wipe awọn mejej! fi ji kan 'ji. Nwọn ko ni orirun meji ọkanṣo-ṣo nb ni nwọn ni. Idi ni yi tį a fi sọ apapọ wọn ni Ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin.

Awọn Ọba fi pįnnu yį siw ju awọn ẹgbẹ mejejį nį įgbagbọ wįpe yįo jẹ lięwọgba nįwaju wọn. Bi orį agbo ko ba koto agba-lagba to fẹ al fi yįo la s! mejį nį. Nįgbatį a ṣ a mọ egun, tį a ṣa a mọ ọran, nwọn gba wįpe ohu tį o tọ tį o sį ba įtan įlẹ Yoruba mu tį ko sį nį mu ẹgan ta ẹgbẹ kįnį tabį ekejį tį nwọn ṣe:

Gbogbo ẹgbẹ mejeji ni nwọn gba ipinnu ti awọn ọba ṣe yi' Bi o ba tilẹ ku awọn kan nibi-kan, ti o ku diẹ ki ọrọ na ye te, iṣẹ wa ni lati lakaka lati tubọ fi yo wọn, ati lati fi han wọn pe otitọ inu ni a fi ṣe gbogbo ohun ti a ṣe ati pe ire ilẹ Yoruba ni a nwa. Agbajọ ọwọ ni a fi nsọ aiya. Ẹ ṣe iranti pe ọkọkan, ejeji ti ejo arin, ni ọmọ araiye fi ari pa. Ọrọ diẹ to fun to moye.

Ẹ jẹki a fi suru ba ara wa lo ẹ maṣe jẹki a binu si ẹnikan Ohun ti yio dara, eṣu ki i jinna sibẹ; Suru ati adura ni a si fi le le eṣu jinna. A bẹ nyin, ẹ jẹki a fi suru si ọrọ wa, ẹ jẹki a pa ara wa pọ di ọkan; Bi a ba ṣe bẹ, gbogbo oke iṣoro wa yio di pẹtẹlẹ pẹlu aranṣe Ọlọrun.

Bi a ba fi ara wa ṣe ọkan, ẹnikẹni ko ni le fi ẹtọ wa du wa. Bi imọ wa ba papọ ni ilẹ Yoruba a o jẹkį awọn ọmọ wa le fi igboiya gbe ori wọn soke, nįbikibi ati nipoki-po ti nwọn wa ni Naijiria ati ni ibomiran tį o r i le gbe wọn de.

Ẹ ma jẹki a wo oni ni-kan ẹ jẹki a fi oju inu wo ọjọ ọ l a pẹlu. Iṣọkan wa nikan ni yio tun ọjọ ọla wa ṣe. O da mi loju wipe gbogbo nyin ni ẹ gba eyi

Idį ni ti fi p e awọn agbagba jakejado įlẹ Yoru ba, t nwọn si pa ara wọn pọ lati ṣiṣẹ fun iṣọkan yi. Ẹ maṣe jẹkį a ṣe e ni ṣọ-kan ti ete nikan, ẹ jẹki a fi agbara wa ṣe iṣẹ iṣọkan na. Ẹ jẹkį a fi ọmọluabi wa ṣe e, ẹ jẹki a fi ọgbọn ati suuru wa ṣe e. Ẹ jẹki a gbagbe ibinu a n a ki a le rẹni ba ṣere.

A bẹ awọn ọdọ ki nwọn lo okun ati agbara wọn si įṣẹ iṣokan yi. Ọrọ yi jẹ wọn logun ju awọn agba lọ nįtori awọn ni yįo kan eyiti o ju nįnu eso įṣọkan na lẹhin ọla.

Ẹ maṣe kọ imọran awọn agba-lagba, iriri awọn agba ti kọ wọn lọgbọn. nwọn mọ gbogbo ibiti koto ati gegele wa ninu igbo— a yo-eda Fun idi eyi, ko yẹ ki ẹ kọ eti-ikun si imoran wọn lati akoko de akoko,

A dupẹ wipe ẹ gba imọran awọn Ọba lati di ọkan, bi ẹni-kẹni ba si ku si ita, ilẹkun ṣi silẹ fun u lati wọ ile. Pẹlu ore-ọfẹ Ọlọrun, awa Yoruba le wi bi Woli nla ni ti wi ni ijọun wipe, 'Ninu ile Baba mi ọpọlọ-pọ ibugbe ni o wa''.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

**E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI-OFE ti o kun fun irohin aladun lososе.**

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o lẹ ri nà nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onjẹ-sise, iná-titàn ati lati mũ fi yáná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

## Your Radio Next Week

# How To Start A Newspaper

How do you start a newspaper? Roy Thomson, the newspaper magnate, was asked this once in the BBC African Service programme AFRICAN FORUM and he said: "You need a lot of money, a lot of determination and a good head for business."

This advice was recalled by David Barlow in another BBC programme, A BOOK FOR TODAY, when he reviewed a book calle "I Bought a Newspaper," by Claude Morris.

"Claude Morris," said Barlow, 'was working on the London 'Daily Mirror' when he go the idea to having his own paper. He found a run-down, almost bankrupt, paper in South Wales, bought it and found he had put himself in bondage. The roof was leaking, the printing machinery needed expensive repairs and the employees were suspicious of the bright and bustling new owner.'

Morris wanted to publish the news, regardless of consequences, but soon found that in a small community it was only too easy to offend people. And that meant that business firms could take away the advartising on which a newspaper depended to keep it solvent.

'Undeterred, Morris pressed on with his one-man campaign,' countinued Barlow. 'His book gives a list of the things against which his newspaper cam aired, and some of them sound pretty bizarre. Others are just the sort of thing newspapers ought to do -and in fect, are doing.'

The book ended as a success story, for Morris valued at £100,000 the newspaper he had bought a few years before for £1,500. 'He had to work hard for his concluded Barlow, and and there were plenty of times when fe t he felt he'd have to throw in his hand, but he hid eventually receive help and encouragement. And by the way, Claude Morris is now working with Roy Thomson.

## And How Be A Journalist

Another BBC broadcast of intrest to journalists and would be journalists was heard when Tunde Oyeleke of Nigeria reviewed "The Practice of Journalism" in the same BBC African series, A BOOK FOR TODAY.

"I don't think there has been a book on journalism as thorough as this one, which deals with all spheres of the profession, he said. "It is produced under the auspices of the National Council for the Training of Journalist and the National Union of Journalists and each contributor was chosen for his extensive experience in Journalism." It was a practical book written by practical men. It is not a book for the young journalist only; older newspaper and radio men would gain immensely by reading it.

Speaking as an African journalist himself Oyeleke said that 'The Practice of Journalism' was of particular interest of Africa. Obviously, it was not possible for all African newspaper men to go overseas to acquire the high standards of journalism that obtained in seuh countries an Britain, but in this book there was now an answer th that problem. The subject covered included reporting style and technique, sub-editing printing business organisation radio and TV journalism, legal aspects of journalism and other essential subjects. "Any journalism who intends to continue with his trade or any who wants to take up journalism, just must have this book on his shelf. I'am happy I have."

## BBC NEXT WEEK

During the coming week programmes in the BBC African Service after the News at 1 o'clock (local time) on 17.81 and 21.615 megacycles in the 16 and 13 metre bands will be as follows:

| | |
|---|---|
| Sunday, March 1 | London Fanfare |
| Monday, March 9 | A Book For Today, Focus On Africa, Around The Town With Sherman Brown, For You At Home. |
| Tuesday, March 10 | A Book For Today, Postmark Africa, African Mirror, Calling Ghana. |
| Wednesday, March 11 | A Book For Today, Focus On Africa, African Forum |
| Thursday, March 12 | A Book For Today, Focus on Africa Discussion Calling Nigeria. |
| Friday, March 13 | A Book For Today, Focus On Africa, World Horizons, Writers' Club. |
| Saturday, March 14 | Showtime. For Parents And Teacher, Calling Sierra Leone. |

YOUR SPECIALIST FOR ALL

BUILDING MATERIALS

BROSSETTE

(NIGERIA) LTD.

WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA

*At your service*

- STOCK
- SPECIAL ORDERS
- TECHNICAL INFORMATIONS

# Egbe Omo Olofin

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Fun ogo Ọlọrun fun iṣọ kan gbogbo iṣẹ Yoruba a da Ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin silẹ lati oni lọ. A fẹ ki gbogbo ọmọ Yoruba ati gbogbo ilẹ Yoruba di ọpọ ẹgbẹ na mu.

A tun tẹnumọ ọ wipe ẹgbẹ yi ki iṣe ẹgbẹ oṣelu; ko si yọ ọmọ Yoruba kankan silẹ. A si ṣe kilọkilọ wipe ninu iṣẹ ẹgbẹ na ki a takete si ọrọ iṣelu ti o le ya wa nipa: Ki a maṣe fa ariyanjiyan oṣelu wọ inu ẹgbẹ na. Ohun ti yio tun ilẹ Yoruba ṣe ni ẹgbẹ yi duro fun.

A le ki ara wa ati gbogbo awọn Ọba-Ọba wa wipe a ku ori're loni nitori a bi ọmọ titun kan loni. Ni ọjọ ti abiyamọ ba bi ọmọ titun ko ni o nfi silẹ wipe ki o ma tọju ara rẹ. Akoko wa ti yio fi fun u l'ọmu; akoko wa ti yio fun u ni agbo akoko wa ti yio fi kọ ti yo fi gẹẹ ki o to di ọmọ ti o to duro. Bẹ gẹgẹ ni ọrọ ti Ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin ri loni.

A dupẹ pupọ lọwọ nyin fun suru ti ẹ fi ka awọn ọrọ wa. A si tun dun lẹkansi fun wiwa ti gbogbo nyin wa si ipade yi. A dupẹ lọwọ awọn ti o ṣe wahala lati ri i wipe ẹsẹ pe dada ninu ipade yi Eyi ko nji jẹ awamọ. Ao ṣe ọpọ iru ọdun bẹẹ. A jumọ ṣepọ a a Ọmọ Ọlọfin ko ni i bajẹ o.

Gunnugun kii ku s'oko iwajẹ

Ayanbọ lọwọ nyun ẹnu
Atẹpẹ l'ẹsẹ ntẹ ọna
Alafia n'ẹ o ba 'le
Adaṣe ni ihun enia;
Iba ki ihun enia;
Eyiti e bẹẹrẹ loni
Pẹlu iba gbogbo Ọba
ati gbogbo Agbaagba
Atiwaiye ọjọ ko ni jẹki
o hun nyin
Atiwọ Ọrun ko ni jẹki
o hun nyin
Ọba Adẹda ko ni jẹki
o hun nyin
Ọba Asẹda ko ni jẹki
o hun nyin
Pẹlu iba gbogbo awọn
to da wa
Ati awọn to ṣẹ wa
Ati iba Olu-aiye, Iba
Odumare
Iba gbogbo ọtọkulu ti
Ọlọrun da
Yio yẹ Ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin kalẹ
Yio si yẹ gbogbo nyin,
Lati irandiran.

## Dokita Omololu Ati Taiwo Jibowu Jalaisi

EKO— Anu ṣe wa lati gbọ iku Dokita O.A Ọmọlolu ati Ọgbẹni Taiwo Jibowu, aburo Olori awọn adajọ-agba Olugbe Olumuyiwa Jibowu, ti o jalaisi lọsẹ yi ninu ile awọn alaisan ti nwọn ti gbe e lọ ni Ibadan.

Ọpọlọpọ awọn enia lọkunrin ati lobinrin ni nwọn lọ si ibi isinku Taiwo Jibowu na ni Ṣọṣi Bẹrẹfurutu l'Eko ni ana.

Ni oni Satide ni nwọn a sin oku Dokita Ọmọlolu.

## Sardauna Ni "Temiyemi"

( O bẹrẹ loju ewe kini )

wipe awọn ti gbe ofin pajawiri kan jade wipe ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe ipade ode tabi ti abẹ ile lai gba aṣẹ lọwọ Ijọba, nwọn ni iru ofin bayi ti wa ni Iwọ Orun ati Ila Orun ti pẹ.

## Awon Omo Egbe Awolowo Gba Awe

EKO-Oloye Awolọwọ ti o jẹ Aṣiwaju awọn ọmọ Ẹgbẹ Ọlọpẹ (A.G) di ẹni ọdun marundinlọgọta, ni ana. Oloye Awolọwọ jẹ ọkan ninu awọn ti Ijọba fi sẹwọn wipe nwọn ndite lati doju Ijọba dele, ninu ọdun ti o koja.

Ọpọlọpọ iwe iki ni ku ọjọbi ni Oloye Awolowọ ti goa ninu ọgba ewọn ni Ikoyi ni ana, lati fi han wipe awọn silwa lẹhin rẹ.

Awọn ẹgbẹ ọdọ ṣe ase nla kan fun irant ọjọ ibi na ni Ibadan ati ni Eko lana. Oloye Wuraọla Esan, ati ọpọlọpọ awọn enia jankanjankan ni wọn lọ ki fun ti ọjọ ibi yi. Ọpọlọpọ nwọn ni nwọn si gba awẹ wipe ki Ọlọrun ki o sọ ọ bọ wa ba awọn lori le.




# AFRICAN SPECIAL

* Full tropicalisation and underbody protection plates
* Strong and comfortable suspension.
* Outstanding road holding.
* Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
* HIGH RESALE VALUE.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street Lagos Phone 23370 Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 457.